# IROHIN IMỌLẸ

*IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA*

No. 1,428 FRIDAY AUGUST 13, 1965 (2D)


## Ọkunrin Kan Ba Ọmọ Odun Mẹrin Lo Pọ!

ILESHA: Ni ọjọ ọjọ Rú ti iṣe ọjọ kọkanla oṣu yi ni Adajọ agba ile ẹjọ kekere ti Ilesha r ase pe ki Ọkunrin Ọdaran kan Emmanuel Ame ẹni ọdun mọkandinlogun yara lọ fi ẹwọn oṣu mẹt jura, ki nwọn tun na ni paṣan mẹfa lori ẹsun pe ọdaran Ọkunrin na ba Ọmọbinrin kan ti iṣe Ọmọ Ọdun mẹrin lo pọ.

Gẹgẹbi ọrọ Ọlọpa to ba Ọdaran na ṣẹjọ ni o ti ṣe alaye pe ni ọjọ kẹsan oṣu kẹfa ọdun yi ni Emmanuel Ame ba omobinrin kan ti iṣe omo odun mẹrin lo pọ ni Abulẹko kan ti a npe ni Owena l'ẹba Ilesha.

Ninu oro ti ọdaran na fẹ fi gba ara rẹ silẹ ni o ti ṣe alaye fun ile ẹjọ pe ki iṣe oro inu ọkan on biko. ṣe wipe omo na lo fi agbara mu on lati ba on lo p eyiti on pẹlu ọmobinrin na jijọ bẹrẹsi ni tage.

Ninu idajo dajo ile ẹjọ na ni o ba ṣe alaye pe kosi oro ti odaran na le so lati fi gba ara rẹ silẹ ti ko ni jiya taṣ na ni o ba so fun pe ki o yara lo fi ẹwon oṣu mẹfa jura.

Ogbẹni Olu Ayoola Sọ Pe:-

# ADAJỌ ṢI ARARẸ LỌNA, O KỌJA IWỌNTUNWỌNSI

IBADAN:- Ni dede agogo mẹrin irọlẹ ana ọjọ ọjọ Bọ ti iṣe ọjọ kejila oṣu yi ni irohin kan de si ile iṣẹ wa lati igboro ilu Ibadan wipe, Ọgbẹni Olu. Ayọọla ẹniti iṣe Agbẹjọro fun awọn enia mẹrinla ti Ijọba Iwọ Orun Naijiria nba ṣe ẹjọ apania lọ si ile ẹjọ gigajulọ fun Orilẹede yi lati lọ pe adajọ agba Ọlọla Adeyinka morgan l' ẹjọ wipe, adajọ na ṣi ararẹ lọna, o si tun rekọja iwontunwọnsi nigbati o gba fun awọn agbẹjọro Ijọba lati ṣe iwadi ẹjọ na ni Ibadan dipo Ijẹbu Ode nibiti ọran na ti ṣẹlẹ

Ọgbẹni Olu. Ayọọla sọ fun ile ẹjọ na wipe, ohunti adajọ agba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ṣe na yatọ patapata ninu ofin eto idajọ, ko si tun ba eto ilana ofin mu

Ninu ọrọ rẹ eyiti o sọ ninu ile ẹjọ na nibi ti o gbe lọ ti iwe ipẹjọ na fun wọn, o sọ ogun ọna pataki ti adajọ na ṣe ṣi ara rẹ lọna ati awọn ohunti adajọ agba na ṣe ti ko dara ti ko si tun ba eto ilana ofin mu.

Ọgbẹni Olu. Ayọọla tun ṣe alaye siwaju ninu ọrọ rẹ wipe, adajọ na ṣi ararẹ lọna nigba ti o sọ wipe nitori ọrọ iṣelu ni awọn en a mẹta kan ṣe ku ni agbegbe Ijẹbu ati nitori awọn nkan ti o ṣẹlẹ ninu ilu na lo mu on pa laṣẹ wipe ki nwọn gbe ẹjọ na kuro ni Ijẹbu-Ode ki nwọn si gbee lọ si ilu Ibadan.

Onirohin wa kan ran wa leti wipe, ni ọjọ Isẹgun ti iṣe ọjọ kẹwa oṣu yi ti adajọ agba Ipinlẹ Iwọ Orun Ọlọla Adeyinka Morgan ṣe idajọ wipe, ki Ijọba wa ṣe ẹjọ apania ti nwọn nba Oloye Samuel Taiwo Ọrẹdẹ n pẹlu Alaiyeluwa Babington Ashaye, Ologere Ọba ilu Ogere ati awọn enia mejila miran ni Ibadan ki nwọn si gbe ẹjọ na kuro ni Ijẹbu— Ode.

Adajọ na ni bi o tile jẹ wipe ohunti on wi yi tabi idajọ ati aṣẹ na yatọ si ohunti oti nṣẹlẹ ni Ipinlẹ na ninu ofin, sibẹ on ṣe idajọ ati aṣẹ na nitoripe awọn enia mẹta ni nwọn ku ni Ijẹbu lẹnulọlọyi.

Ṣugbọn ni ipari idajọ rẹ, adajọ na sọ wipe iwadi ẹjọ na nikan ni on sọ wipe ki wọn wa ṣe ni Ibadan, ki iṣe ẹjọ awọn enia na.

Ni ipari ọrọ rẹ, adajọ na wa kilọ fun awọn agbẹjọro Ijọba wipe ki nwọn tete ṣe ẹjọ awọn enia na lasiko ki awon enia na ma ṣe pẹ pupọ ju bi o ti ṣe yẹ lọ, ki nwọn le tete pari gbogbo ohunti nwọn ba fẹ ṣe ninu ẹjọ na.



Olu Ayọọla

## Ẹ KU EWU OKO O!



IKẸJA: Gbogbo ile lo ku ṣọṣọ ti ẹsẹ ko si gbe,i fun ogunlọgọ ọkẹ aimoye awon enia ti nwon wa si ibudo ọkọ ofurufu ni alẹ Ijẹta ti iṣe ọjọ ojo Ru ti iṣe ojọ kọkanla oṣu yi nigbati Ọgbẹni Arthur Bottomley, Minista Alamojuto eto awon Ilẹ Okere fun Ijọba Gẹẹsi ati Iyawo r pelu awon akọwe won de si Eko lati wa bẹrẹ irinajo ọjọ mọkanla si Orilẹ Ede yi

Ki awon enia to de ni gbogbo awon Minista Dokita, adajo, Loya, Ijoye ati awon enia sarakisaraki pẹlu gbogbo awon oniṣẹ Ijoba ni nwon ti duro. ti nwọn si nreti awọn enia na lati de

Irohin ile iṣẹ Aṣoju Ijọba Gẹẹsi ni Naijiria fi ye wa wipe, Ọlọla Arthur Bottomley yio wa ni Naijiria fun ojo mokanla. Ninu irinajo rẹ si orilẹ ede yi Ọlola Bottomley yio de gbogbo awon Ipinlẹ Mẹrẹrin yika ki o to pada si Eko lẹhin na ni yio ba awon Oniwe Irohin soro ni ibudo oko ofurufu ni Ikẹja ki o to kuro lo si ilu Oyinbo.


WO OJU EWE KẸFA

# Iwe si Olotu Irohin Imole

## Oju Ona Mushin Nfẹ Atunṣe

Olotu;- Inu mi yio dun bi o ba le ba mi ṣe ikede yi fun awọn Ijọba Ibilẹ Mushin pe ki nwọn mura giri lati ba ni tun gbogbo awọn opopo ti o wa larin Mushin ati Shomolu ṣe. Awọn wọnyi kiṣe ti Ijọba apapọ lati ṣe rara.

Orişirişi ọna abuja lo wa lọna Shomolu lati gba yọ si Eko şugbọn awọn Ijọba Ibilẹ Mushin ati Shomolu ko kọ bi ara si eyi rara, lọwọlọwọ awọn Moluẹ ti o yẹ ki nwọn ma lọ gba Ikeja eyiti o jẹ oke isoro diẹ fun Moluẹ lori gada. nwọn ni kan lati Gareji Mushin eyiti o jasi University ti Eko tabi Yaba tabi Suru lere, la ti ọjọ kinni oşu kẹjọ ọdun yi ti nwọn ti sen o ni gbogbo mọto ti ngba ibẹ lọ si Eko dipo ki Ijọba Ibilẹ Mushin gbe Katapila kọja lori ọna ki uwọn si tunşe nwọn ko şe eyi şugbọn ninu wọn to nwa s'Eko na ngba ọna yi kanna.

N torina a fi iyọnu Ọlọrun be awọn Igbimọ ti o wa lori aga lasiko yi ki wọn jọ fi ori kan ori lati le tete ba wa tun gbogbo opopo ati awọn ọna abuja ti o wa ni Mushin ati agbegbe rẹ şe

Ọlọrun yio ba yin tun ile ati ọna yin şe o.

Emi ni,
Angelina Adenji.

A tun nfẹ ẹrọ omi ti a o ma mu bi ẹrun bade, omi ti a nmu ko dara torara, igbamiran a nkọ arun ninu omi ti a nmu

Ẹ ma gbagbe awa ti a dibo fun nyin, nitoripe, asiko tun fẹrẹ de ti ẹ o tun ma bẹ wa pe, ki a wa dibo fun yin mo fi Ọlọrun bẹ nyin, ẹ ma gbagbe ileri ti ẹ şe fun wa o

Olotu ọkọ ọba ko ni şa nyin lẹsẹ o.

Emi ni
M. Ọla. Arinọla
ESIẸ

## Ilu Esiẹ Nfẹ Iranlowo

Yio şe didun inu mi bi olo tu gba mi ni aye ranpẹ ninu iwe rẹ oloyinmomọ lati kesi awọn aşoju ninu ile Igbimọ Aşofin Apapọ Ijoba ki nwọn ki o mu ileri ti nwọn şẹ fun wa şe ki nwọn ki o maşe gbagbe nitoripe asiko nla.

Ilu Esie nfẹ oda loju gbo bo ona ti o wọ ilu na ati awọn ilu to wa lagbegbe ilu Esiẹ. nitoripe ilu ti ko tobi to ilu Esiẹ ni oju ọna ọloda ati awọn nkan meremere miran ti o njẹ ki ilu dara.

## Njẹ Siga Mimu Dara?

Olotu Jọwọ gba mi ni aye ranpẹ yi ninu gbajumọ iwe Irohin Imolẹ rẹ lati kesi Ijọba Apapọ pe ki nwọn pa Siga mimu rẹ, ati lati tun bere lọwọ awọn onkawe Imọlẹ boya Siga mimu dara tabi ko dara.

Mo fe ki awọn onkawe Irohin Imọlẹ fi ye mi ohun ti Siga mimu nşe lara, ati idi rẹ ti o fi wu awọn ti o mu mo si tun fẹ ki ẹnyin onkawe mi tun so fun mi pẹlu bi o ba yẹ ki Ijọba şe ofin lati fi pa siga mimu rẹ ki awọn ti o si nko wọlu maşe ko wolu mọ nitori emi ko ri on ti giga nşe lara ti ko şe pe o tun nko aisan ba awọn ti o mu ni.

Ni idi eyi mo fẹ ki enyin onkawe Irohin Imọlẹ so fun mi bi siga mimu ba dara pe bi o ba yẹ ki Ijọba şe ofin lori siga mimu nilẹ yi.

Ọrọ na ku si yi lọwọ o ẹ la ye mi o.

Emi ni
Latifu Babalọla
EKO.

## Anfani Nla De Fun Gbogbo Awọn Ti Nlo Gulu

TI A FI NLẸ PAKO TABI IWE

Gulu Funfun eyiti a ti şe wa lati ilu Oyinbo ti o wa ninu Igo Funfun oorun rẹ dabi lọfinda ti a nbu sara Irohin ko to afojuba tete yara lọ ra tirẹ lodọ :
Y. AROWOLO NI 118, Griffth Street, E. B Lagos

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igo kekere | 6/- | Igo Nla | 8/- |
| Igo mejila nla | £4 4/- | Igo Kekere | £3 |

## Ipolowo Oja Rẹ ko Ti Yege

*Nitoripe*
O KO TI POLOWO ỌJA RẸ
SINU IWE IROHIN IMOLẸ
T'ODUNKA FUN GBOGBO ENIA

KỌWE IPOLOWO ỌJA RẸ SI
ADVERTISEMENT MANAGER
IROHIN IMOLẸ
16 Bamgbọşe Street, Phone 21985 Lagos

## Bọ Lọwọ Oşo Ati Ajẹ

Iwe egbogi Ajẹbidan 25/- mejila £2
Iwe Ilana Ifa Iyanrin tirẹ ati etutu rẹ pẹlu Iwosan 20/- mejila £2 5/
Iwe Egbogi Awogba Arun meji 40/-
Turari isẹgun Ajẹ Oşo ati awọn abanije O wa fun itaja pẹlu alakala Pangolo 10/- Pakẹti 2/- Ki işe ti ẹnu fifọn bi o ra ninu awọn ọja yi aabo ti o nipon ni ile aiye ni yio wa lori rẹ ati awọn ẹbi rẹ.

Fi owo ranşẹ si

J O SHOYINKA
5 Alaba, Street
Odu aborẹ Mushin.

BERE EGBOGI ARỌN
## CORSIVERA

Oiulowo egbogi atamatase ti o daju fun iparun awọn "ARỌN" buruku gbogbo lara enia, papa tabi ni pataki fun ARỌN latanlatan tabi arọn kinişa ti o ma mu idiwọ wa fun ẹgbaagbeje obinrin lati loyun tabi ti o ma nba oyun jẹ lara Obinrin.




B, si ni egbogi yi dara fun gbogbo ẹniti aran agbẹdu Igba aya, ọna ọfun, sis lẹhin bi ake tabi aran oju pẹlu Meji irufọ egbogi arọn yi kosi ni gbogbo ilẹ Naijiria isẹ rẹ si daju. AKIYESI PATAKI

Ri daju wipe o ti re eko lọ ọwọ ati ẹsẹrẹ daradara ki oto lo egbogi arọn yi gẹgẹbi awọn Jaman ti o şe ti juwe lilo re Fun agbalagba nikan ni o wa fun. Berre orisirisi egbogi arọn fun ọmọde pẹlu wọn nbẹ fun tita ni şọbu awọn

ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street, Yaba.
Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street Lagos

NIGERIAN MEDICINE STORES
4 Tinubu Square, Lagos

ATI NI ŞOBU
IŞẸ OLODUMARE DISPENSARY OKEBỌLA
IBADAN

# Nwọn Yin Ibọn Pa Ọkunrin Agbẹ Kan

AGO-IWOYE Ni kutukutu owurọ ọjọ Aje ti işe ọjọ kẹsan oşu yi ni irohin kan de ọwọ wa pe awọn Ọlọpa mu Ọkunrin agbẹ kan ti nwọn lero pe on lọ pa Ọkunrin agbe kan ti nwọn ri oku rẹ loju ọna oko kan ni ilu Ago-Iwoye l'ẹba Ijẹbu-Ode.

Irohin na tun fi ye wa pe awọn Ọlọpa tun mu awọn enia mefa lati sọ ti ẹnu wọn lori iku ọkunrin agbe ati pe ọrọ ti awọn ọlọpa yio gbọ lẹnu awọn enia na yio ran wọn lọwọ lati mọ awọn enia ti yio ibọn si ọkunrin ẹgbẹ na.

Irohin awọ ọlọpa tun fi ye wa pe okunrin na Adeen ga Ajayi ti işe eni ọdun mo kanleladọta ni nwọn tun şe alaye pe ibọn ni awọn en a to pa oku rin na yin funun

Oniwe irohin wa ti o lọ si Ago-Iwoye nibi ti işẹlẹ na ti şẹlẹ tun fi ye wa pe nigbati awọn enia okunrin na ko ri ki o pada wa sibe lati oko ni nwọn ba lọ fi ọran na sun ni Tesan awọn Ọlọpa.

Lẹsekẹsẹ ti awọn ọlọpa ti gbọ ọrọ na ni nwọn ba bẹrẹsi ni wa ọkunrin na kiri inu igbo eyiti o jẹ pe nwọn fi ri oku rẹ ni ẹba oju ọna igbo kan ti awọn eera ti bo ọkunrin na lara pẹlu eşinşin ti nwọn si bo ara rẹ yika.

Irohin na tun fi ye wa pe ni dede agogo mejila ọsan ọjọ Aiku ti awọn enia ọkunrin na to ri okun rẹ ni inu igbo. Awọn enia ọkunrin agbẹ na tun şe alaye fun Oniwe Irohin wa pe ni ọjọ Abamẹta ti işe ọjọ keje osu yi ni ọkunrin na sọ fun awọn enia rẹ pe on fẹ lọ si oko on eyiti ko fi pẹ bẹ wale mọ ti o fi jẹ wipe oku rẹ ni nwon si gbe pada.

Nigbati awon enia okunrin agbẹ yi reti rẹ titi, ti nwon ko ri ni nwọn ba lo fi ọrọ na sun awọn ọlọpa ki o to di wipe nwon bẹrẹsi ni wa inu igbo igbo kakiri ki nwọn to ri oku ọkunrin na ti awọn eera ti bo gbogbo ara rẹ. Ọkunrin agbẹ na ngbe ni nomba 8, Oke-Ebute Street Ago-Iwoye. Awon ọlọpa ti nşe iwadi lori iku ti o pa Ọkunrin na bayi

## ★ YẸ IRAWỌ RẸ WO ★

AQUARIUS: (Jan 22 Feb 20) Ara rẹ yio le loni lati gbajumọ işẹ rẹ sugbọn ki o tọju alafia ara ki o si fẹ lọ si ajo ki o lọ si aye ibiti ko si ariwo rara.

PISCES: (Feb 21 Mar 20) Iwọ yio ri ẹre pupọ jẹ ni owurọ yi ki o si tete mura si işẹ rẹ ki aarẹ miran to de.

ARIES (Mar 21 April 20) Ohun kan wa ti koiti da ọ loju kedere ni owurọ yi şugbọn nigbati o ba şe okan na yio dara ba awọn ọrẹ rẹ sọrọ pọ nipa iyọnu ti o ba desi ẹ ki o si fetisi imọran wọn.

TAURUS (Apr 21 May 20) Orişirişi nkan ni yioma şe ọ loni şugbọn işẹ rẹ na yio pọ ni akoko ọsan ati ni irọlẹ

GEMINI (May 21 June 21) Ọjọ ayọ ni oni yi jẹ gbo gbo ede ko yede ni yio kuro patapata larin awọn ebi rẹ bi o ba si fẹ lọ si ajo ba awọn enia atata rin papọ nwọn osi fi işẹ kan lọ ọ.

CANCER (June 21 July 22) Bi a ba le lo laaiaye ati ọgbọn işẹ kan ti o wa fun ọ laip; yi yio fo lọ maşe jẹki nwọn pokiki rẹ kakiri awọn ọrẹ rẹ to ni iran'ọwọ fun ọ.

LEO (July 23 Aug 22) Işẹ rẹ yio pọ loni yio si mu idamu diẹ lọwọ o le jẹ wipe ọrọ ni nwọn ma gbe siwaju rẹ şora gidigidi lọdo awọn alayọnusọ ti yio fẹ dasi ọrọ na

VIRGO (Aug 23 Sept 23) Şe inawo nipa işẹ rẹ ki oba le ri ere jẹ tele awọn ore re ki o si wọ inu ẹgbẹ wọn

LIBRA (Sept 24 Oct 23) Ijọgbọn kan ti o ti wa ninu ọkan rẹ yio pari loni iwọ yio si ri idẹra tobẹ nigbati o ba pari işẹ rẹ tan iwo yio bẹrẹ omiran iwọ yio gbo iro hin ayo

SCORPIO: (Oct 24 Nov 22) Gbolohungbodo yio wa ni owurọ şugbọn ailera yio wa fun awọn enia rẹ ni ọjọrọ maşe fi ti ehin şe, idẹra mbọ ri laiṣẹ

SAGITTARIUS: (Nov 23 Dec 21) Bi o ba lọ şe abẹwo awọn ọrẹ tabi enia rẹ, iwọ yio ri ere pupọ jẹ, Ba awon ọta rẹ pari ija, ọjọ oni dara lati ra ọja titun, iba şe pọ iwọ pẹlu awọn ọrẹ rẹ yio dara.

Capricorn: (Dec 22 Jan 21) Işẹ yio pọ fun o loni, şugbọn alafia yio de si nigbati o ba wa, iwo yio si le şişẹ daradara, iwo yio si gbo irohin lati Okere wa


EGBOGI AWỌN ILU FARANSE

**TESSYDRE**

Fun Ọmọ—Ọwọ ati Ọmọde gbogbo



Tessydre jẹ ojulowo egbogi hauuhauu ti meji irufẹ rẹ kosi kakiri igboro ilu Naijiria fun itọju ọmọ ọwọ ati ọmọde lati le jẹ ki wọn ma hu EHIN ẹnu wọn pẹlu irọrun laisi wahala rara tabi aiko le sun yala lọsan fun awọn iya wọn gbogbo Ọgọrun orişirişi egbogi bayi ni wọn npolowo sinu ẹrọ gbohungbohun ati sinu iwe kika lojojumọ şugbọn ko si eyi ta le fi we egbogi Tessydre rara o, Ọlọgbọn di ori ẹja mu pupọ ninu awọn ara ilu Saro ati awọn Agọnyin (GHANA) mọ egbogi yi dajudaju on ni awọn si nlo fu awọn ọmọ ti wọn ba şẹşẹ bi titi fi di okan bi ọmọ ọdun mẹwa gbako. Kosi wahala tabi iyọnu inu rirun ọka ori aiperi ori inu iwọ osi fẹkun fẹkun owo, kokoro ara lapalapa ara gbigbona igbẹ şişan gburu tabi aikolokun ninu ara, sisu inu kun nun aiorun ati orisirisi awon amodi tabi sisan ti o ma eyọ awọn ọmọ ọwọ lẹnu nigba Ehin HIHU gbogbo Tessydre a ma mu ki ẹhin ẹnu ọmọ rẹ lagbara gidigidi ati san pẹlu.

Awọn ọmọ ti nlo egbogi yi ki saba ma sarẹ rara niwọn igbati nwon ba ti nlo deede, ti otutu ki si le ri aye ati duro ni Igbaiya wọn ti wọn njẹun daradara nwon si ngbadun pẹlu yio si jẹ ki erigi san pẹlu.

NIGERIAN MEDICINE STORES
4 Tinubu Square Lagos

# Ọmọ Yoruba Ẹ Ṣe Ara Nyin L'ọkan

**Lati Ọwọ J. Ade Afolabi Igbaja**

Olotu iwe Irohin Imọlẹ ku Iṣẹ o,
Ọmọ Adeoṣun o ku afogbọn ṣe
Ẹnyin Aliba ṣiṣẹ rẹ gbogbo o nyin ni mo ki;
Ẹ ku lakaye ẹ si ku ọgbọn inu
Oluwa ko ni jẹki ẹ daran Ijọba
Ọta adani waye ko ni jẹki ẹ ṣiṣe
Ẹ jọwọ mo bẹ nyin ni oruko Ọlọrun
Mo bẹ nyin ni oruko Oduduwa
Ẹ ba mi tẹ ọrọ yi jade fun awọn ọmọ
Iya mi. Awọn baba wa lo ma npa lowe pe
Bi ezun eri ba jo re, ori a ya ni toto O ṣe bi o ṣe o.
Ọmọ Yoruba ọjọ wo ni ẹ tun ma fi ye silẹ?
A ni ọjọ wo ni ẹ o to ronu
O tito ti de ọja o kuta
Mo ṣe bi pẹlu owo lowo ni a nra eke,
Ẹ wo iru ipo ti Ẹlẹda ti fi wa si
Mo ni lati igbati a ti da ile aiye
Ẹ wo iru ipo ti a wa lode oni
N bo ri ogun yi di wa?
Ah! ọmọ Yoruba; Ẹ ronu lori eyi ti a wa loni
Ẹ wo ọjọ ti a ti nja fun Ominira,
Nigbati ominira na wa de tan
O wa so ti wa di isira?
Ọrọ yi kan Oloye Ladoke Ọmọ Akintọla
Baba Ọmọdele ọkọ Faderera;
O si wa gba awọn janduku kiye
Lati da ilẹ Yoruba ru.
Lati ṣe eke si ilẹ Oduduwa
Jọwọ Baba Ọmọdele ronu si
La'i ọjọ ti ẹ ti nba ọrọ yi tọ
Pẹlu Baba wa n'Ikẹnnẹ
Ọlọgbọn d'ori ẹja mu baba Oluṣẹgun
Ti ẹ ti jumọ nba bọ ti ko tẹ ti ko wọ ọ
Ti aiye nnoju ti igba si n d-u n yungba
Ti ogun wa w ọ l e de l'ọsan gangan
Ṣugbọn ọrọ na ko deede ri tẹ
Ṣebi ẹniti akọ ni ika to ṣe.
Mo ni o ti si aba rẹ ninu
Ṣe bi awọn ba kọ ọ si Awolọwọ
Ti oba si sọ imọ awọn di asan nigbana
Ṣe ti ọmọ Yoruba ko ni di rudurudu
Mo ni iya ko ni ma jẹ onile ati alejo
Ṣe ọmọ Yoruba ko ni di ero ẹhin
Ẹ yin ẹ wo iye ẹmi ti o ti nsofo
Nigbati Awolọwọ ko si n i l e
Baba Ọmọtọla ọkọ Dide - O l u
Ko si ni ijọ, ijọ ko kun
Ko si ni ilu, ilu ko toro
O jade nile gbogbo ile di alariwo
Edumare Ọba Oke ki o ba wa dari
Awolọwọ wale.
Ọba Adaniwaiye
Ba wa dari Baba Oluṣẹgun wale dandan
Oloye wa Maṣẹkodunmi o ṣeun
Ọmọ Ọba Ademọla ẹ ku igbiyanju
Oloye wa T. O. S. Benson nko gbagbe rẹ
Paapa julọ Ọlọla na Alhaji Dauda Adegbenro
Gbogbo akitiyan nyin lori ilẹ Yoruba
Ọlọrun Ọba ko ni jẹki o ja si asan
Nitori ẹ aba ti Alagẹmọ ba da, on ni oriṣa maa gba
Ni pataki julọ ẹnyin baba wa Alaiyeluwa, Alaṣẹ ekeji oriṣa
Ọba Ọni Ile-Ifẹ, Alake ti Abẹokuta
Awujalẹ ti Ijẹbu-Ode ati Oṣemowe ti Ondo
Mo kesi gbogbo ẹnyin Ọba ilẹ Yoruba
Mo ki nyin ẹ ku bi aiye ti ngba
Ṣugbọn mo fẹ ran nyin leti pe
Ko si bi o tima buru baje to, Ẹnyin ni baba gbogbo wa
O yẹ ki e la gbogbo agbara nyin
Nitori Ọba to jẹ ti a fi iyun bolẹ, aiye a ma ri ti wọn sọ
Ati eyiti a jẹ ti o si ba ilẹ jẹ, Babanna aiye yio ma sọ tirẹ ni
Nitori a gbo ti Dafidi Ọba Israeli
Beẹni a ko sa gbọ ti Nebukadinassari
Nitorina mo bẹ nyin, Bi alafia on Irora
Yio ti ṣe pada si ilẹ Yoruba.
Eleyi di owo nyin o
Ni ipari oro mi ẹ ba mi ko orin yi:-
1 Tani o gbe Yoruba dide ?
Ọro Yoruba ko po,
Eyi to jẹ iyanu ni pe;
Imọ wọn ko ṣọkan
2. Tani o gbe Yoruba dide?
Ọta Yoruba ni'pa
Ọmọ Yoruba o d'owọ nyin
Ẹ ronu jinlẹ o.
3. Ẹ jẹki a bẹ Ọlọrun wa
Ko fun wa n'irẹpọ,
K'ama ṣere f'eya miran
N'inu Ijọba ilẹ wa
4. Ọmọ Oduwa ẹ ji giri
Ẹ pa ẹtanu ti
K'e jẹ ka ṣe 'ra wa lọkan
Fun ire ilẹ wa

# Asọbade Orire Are Bọọlu

| | | |
|---|---|---|
| Chester U. v Liverpool | 2 | 2 |
| Barrow v Workington | x | 2 |
| Bournemouth v South'ton | 1 | x |
| Brentford v Ipswich | 1 | x |
| Brighton v Charlton | x | 1 |
| Bristol C- Swindon | 1 | 1 |
| Cambridge U v Barnsley | 1 | 2 |
| Cheltaham v Swansea | 2 | 2 |
| Colchester v Southero | x | x |
| Coventry v Not'ham F. | x | 3 |
| Crystal Palace v W. Ham | 1 | x |
| Huddersfield Sheffield U. | 2 | 2 |
| Leeds v Sounthorpe | 1 | 1 |
| Millwall v Norwich | x | 2 |
| Portsmouth v. Q P R | 1 | x |
| Stockport v Oldham | x | 1 |
| Sunderland v Spartn | 1 | x |
| Torquay v Bristol R | x | x |

## Scottish League Cup

| | | |
|---|---|---|
| Clyde v Aberdeen | 1 | x |
| Dundee v U. v Celtic | 1 | x |
| Falkirk v Hibernian | x | 2 |
| Hear's v Rangers | 1 | 2 |
| Motherwell v Dundee | x | 2 |
| Partick v Dunfermline | x | 2 |
| St J'stone v Kilm'nock | 2 | 2 |
| St Mirren v Morton | x | x |
| Albion v Q of South | x | 2 |
| Alloa v East Fife | 1 | x |
| Ayr v Stenhousemuir | x | 2 |
| Bearwick v Third Lanark | 2 | 2 |
| Cowdenbeath v Hamilton | 2 | 2 |
| Dumbarton v E. Stirling | 1 | 2 |
| Forfar v Montrose | 2 | x |
| Queens Park v Arbroath | x | 2 |
| Raith v Stirling | 1 | 2 |
| Stranraer v Airdrie | x | x |

## Scottish Reserve Matches

| | | |
|---|---|---|
| Celtic R v Dundee U R | 1 | 1 |
| Dundee B v Motherwell | 1 | x |
| D'line R v Partic R | x | 2 |
| Hibernian R v F'kirk R | 1 | x |
| K'nock R v St. J'stone R | 1 | 1 |
| Morton R v St Mirren R | x | 1 |
| Rangers R v Hearts R | x | x |

## First Half

DRAWS (11): Queen's Park Ayr, Albion Dun'mline, St. Mirren. Partick Thistle, Motherwel- Torquay, Stockport, Coventry, Brighton.
AWAYS (6): Swansea, Sheffield United, Kilmarnock, Third Lanark Hamilton. Montrose
HOMES (14): Bournemouth, Brentford, Bristol City, Crystal Palace Leeds, Sunderland, Hearts, Celtic Rovers, Hibernian, Aloa, Dumbarton, Raith Dundee Rovers Dundee Untend

## Full-Times

DRAWS (8) Dallrae Port, Ailoa. Forfar mouth Colchester Stock Stranreaa St Mirren Clyde
AWAYS (6): Rangers Dunde. Dun'fermline Kilmarnock Queen of South Hamilion
HOMES (10): Brighton Bristol City Leeds Sunderland Celtic Rovers St Johnstone Rovers St Mirren Rovres Brentford Portsmouth Aliea

